*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

## Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

# Àláàfíà Dé!

Àwọn ìpọ́njú tí ó ń bani lẹ́rù ló wà láiyé lóde òní: Ìṣòro àìríná-àìrílò, àìsàn ti ara àti ti ọpọlọ; ìkórìíra ọmọnìkejì àti ẹ̀tanú; ìwà-ipá ìbọn, ìpániláyà, ìwà-ipá abẹ́lé àti ìfiyàjẹni; ìwà ìrẹ́nijẹ, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ó lè wù ọ́, láti lérò pé ohun gbogbo ló ti tẹ̀ ọ́ lọ́wọ́, àti pé ìwọ kò nílò ǹkankan láti ọwọ́ Krístì. Ò ń gbẹ́kẹ̀lẹ́ agbára rẹ, ọgbọ́n rẹ, ọrọ̀ rẹ, tàbí àwọn àyànfẹ́ rẹ, fún ìwàláàyè rẹ; ṣùgbọ́n òtítọ́ ibẹ̀ gan-an ni wípé, ohun gbogbo kọ́ ló ní ìdánilójú ní ilé-aiyé. Agbára lè kùnà nítorí àìsàn ara. Ọgbọ́n lè dínkù nítorí àìsàn ọpọlọ tí ó lágbára. Ọrọ̀ lè pòórá láàárín ìṣẹ́jú kan. Ó ṣeé ṣe kí àwọn àyànfẹ́ tí a gbẹ́kẹ̀lé fi aiyé sílẹ̀ lójijì. Àwọn òmíràn á máa já wa kulẹ̀ bí ìfẹ́ wọn ṣe ń tutù. Àlàáfíà tí Jésù Krístì ń fúnni

*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!

*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL
~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé

www.divineliterature.org
www.doveletters.org

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023

Àláàfíà Dé!

Àwọn ìpọ́njú tí ó ń bani lẹ́rù ló wà láiyé lóde òní: Ìṣòro àìríná-àìrílò, àìsàn ti ara àti ti ọpọlọ; ìkórìíra ọmọnìkejì àti ẹ̀tanú; ìwà-ipá ìbọn, ìpániláyà, ìwà-ipá abẹ́lé àti ìfiyàjẹni; ìwà ìrẹ́nijẹ, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ó lè wù ọ́, láti lérò pé ohun gbogbo ló ti tẹ̀ ọ́ lọ́wọ́, àti pé ìwọ kò nílò ǹkankan láti ọwọ́ Krístì. Ò ń gbẹ́kẹ̀lẹ́ agbára rẹ, ọgbọ́n rẹ, ọrọ̀ rẹ, tàbí àwọn àyànfẹ́ rẹ, fún ìwàláàyè rẹ; ṣùgbọ́n òtítọ́ ibẹ̀ gan-an ni wípé, ohun gbogbo kọ́ ló ní ìdánilójú ní ilé-aiyé. Agbára lè kùnà nítorí àìsàn ara. Ọgbọ́n lè dínkù nítorí àìsàn ọpọlọ tí ó lágbára. Ọrọ̀ lè pòórá láàárín ìṣẹ́jú kan. Ó ṣeé ṣe kí àwọn àyànfẹ́ tí a gbẹ́kẹ̀lé fi aiyé sílẹ̀ lójijì. Àwọn òmíràn á máa já wa kulẹ̀ bí ìfẹ́ wọn ṣe ń tutù. Àlàáfíà tí Jésù Krístì ń fúnni

nìkan ló lè gbé ọ dúró nígbà tí àwọn ìṣòro ìgbésí aiyé bá dé ọ̀dọ̀ rẹ. Ká tiẹ̀ wá sọ pé ìṣòro ìgbésí aiyé kankan ò súnmọ́ ẹ rí - o ṣì nílò o àlàáfíà yìí láti gbádùn ohun tí o ní. Kò sí ohunkóhun tí a kò lè borí bí a bá ní álàáfíà Rẹ̀. Jésù Krístì ni Ọmọ-Ọba Aládé Àlàáfíà (Àìsáyà 9:6). Ó ṣèlérí àlàáfíà àti ìtùnú fún gbogbo àwọn tí wọ́n wà nínú ìdààmú; tì a di ẹrù wíwo lé lórí, bí wọ́n bá wá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ (Mátíù 11:28-30). Yàtọ̀ sí pé Ọmọ-Ọba Aládé Àlàáfíà ni Jésù Krístì, nípasẹ̀ Rẹ̀ ni à ń rí ìbùkún gbà ní òtítọ́ àti lọ́pọ̀ yanturu, pẹ̀lú. Láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run Bàbá ni gbogbo ẹ̀bùn rere àti ẹ̀bùn pípé ti wá (Jákọ́bù 1:17). Nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀ ni a sì ń rí àwọn ẹ̀bùn yìí gbà (2 Kọ́ríńtì 1:20, 1 Kọ́ríńtì 8:5-6). Àmọ́, ìwọ kò lè ní irú àlàáfíà tí à ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ yìí, tí o kò bá jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì.

Ó lè dà bíi pé òkìkí, ọrọ̀, agbára, àti àwọn ohun ìgbádùn inú aiyé ń fún ọ ní àlàáfíà; ṣùgbọ́n ó wàá ríi pé gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyí ń fúnni ní ìtẹ́lọ́rùn fún ìgbà díẹ̀ lásán ni. Nípasẹ̀ Jésù Krístì nìkan ni a ti lè ní ìrírí àlàáfíà tòótọ́, tí yóò pẹ́ títí (Jòhánù 14:27). Àwọn ènìyàn tí wọ́n wà ní ipò ìbátan pẹ̀lú Rẹ̀ ń ní ìrírí àlàáfíà tí o kọjá ohun tí ẹ̀dá lè lóye, bó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n lè máa dojú kọ ìpèníjà kan tàbí òmíràn (Fílípì 4:7). Wọ́n kì í dààmú. Ọkàn wọn balẹ̀. Wọ́n ń dúró gbọn-in nígbà ìṣòro, wọ́n sì ń borí ìṣòro náà. Yàtọ̀ síyẹn, wọ́n ń gbé ìgbésí aiyé òmìnira tí ó ti bọ́ lọ́wọ́ hílàhílo àti àwọn ọ̀ràn bíi: ìbẹ̀rù ohun àìmọ̀, ìgbèkùn ẹ̀ṣẹ̀, ẹ̀bi ẹ̀ṣẹ̀ tó ti kọjá, àti èrò ìdájọ́ tó ń bọ̀ lọ́jọ́ iwájú. O nílò o àlàáfíà tòótọ́, tí yóò pẹ́ títí nínú aiyé búburú àti àìdánilójú tó kún fún ìwà ìbàjẹ́, tí a ń gbé nísinsìnyí. Ẹ̀bùn yìí wà fún ọ láti jèrè, ní kété tí o bá ti wà ní ipò àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run, nípa gbígba Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ. Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti gbà á. Yàn, láti gbà á lónìí!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbési aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*

nìkan ló lè gbé ọ dúró nígbà tí àwọn ìṣòro ìgbésí aiyé bá dé ọ̀dọ̀ rẹ. Ká tiẹ̀ wá sọ pé ìṣòro ìgbésí aiyé kankan ò súnmọ́ ẹ rí - o ṣì nílò o àlàáfíà yìí láti gbádùn ohun tí o ní. Kò sí ohunkóhun tí a kò lè borí bí a bá ní álàáfíà Rẹ̀. Jésù Krístì ni Ọmọ-Ọba Aládé Àlàáfíà (Àìsáyà 9:6). Ó ṣèlérí àlàáfíà àti ìtùnú fún gbogbo àwọn tí wọ́n wà nínú ìdààmú; tì a di ẹrù wíwo lé lórí, bí wọ́n bá wá sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ (Mátíù 11:28-30). Yàtọ̀ sí pé Ọmọ-Ọba Aládé Àlàáfíà ni Jésù Krístì, nípasẹ̀ Rẹ̀ ni à ń rí ìbùkún gbà ní òtítọ́ àti lọ́pọ̀ yanturu, pẹ̀lú. Láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run Bàbá ni gbogbo ẹ̀bùn rere àti ẹ̀bùn pípé ti wá (Jákọ́bù 1:17). Nípasẹ̀ Ọmọ Rẹ̀ ni a sì ń rí àwọn ẹ̀bùn yìí gbà (2 Kọ́ríńtì 1:20, 1 Kọ́ríńtì 8:5-6). Àmọ́, ìwọ kò lè ní irú àlàáfíà tí à ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ yìí, tí o kò bá jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún Krístì.

Ó lè dà bíi pé òkìkí, ọrọ̀, agbára, àti àwọn ohun ìgbádùn inú aiyé ń fún ọ ní àlàáfíà; ṣùgbọ́n ó wàá ríi pé gbogbo àwọn nǹkan wọ̀nyí ń fúnni ní ìtẹ́lọ́rùn fún ìgbà díẹ̀ lásán ni. Nípasẹ̀ Jésù Krístì nìkan ni a ti lè ní ìrírí àlàáfíà tòótọ́, tí yóò pẹ́ títí (Jòhánù 14:27). Àwọn ènìyàn tí wọ́n wà ní ipò ìbátan pẹ̀lú Rẹ̀ ń ní ìrírí àlàáfíà tí o kọjá ohun tí ẹ̀dá lè lóye, bó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n lè máa dojú kọ ìpèníjà kan tàbí òmíràn (Fílípì 4:7). Wọ́n kì í dààmú. Ọkàn wọn balẹ̀. Wọ́n ń dúró gbọn-in nígbà ìṣòro, wọ́n sì ń borí ìṣòro náà. Yàtọ̀ síyẹn, wọ́n ń gbé ìgbésí aiyé òmìnira tí ó ti bọ́ lọ́wọ́ hílàhílo àti àwọn ọ̀ràn bíi: ìbẹ̀rù ohun àìmọ̀, ìgbèkùn ẹ̀ṣẹ̀, ẹ̀bi ẹ̀ṣẹ̀ tó ti kọjá, àti èrò ìdájọ́ tó ń bọ̀ lọ́jọ́ iwájú. O nílò o àlàáfíà tòótọ́, tí yóò pẹ́ títí nínú aiyé búburú àti àìdánilójú tó kún fún ìwà ìbàjẹ́, tí a ń gbé nísinsìnyí. Ẹ̀bùn yìí wà fún ọ láti jèrè, ní kété tí o bá ti wà ní ipò àjọṣe pẹ̀lú Ọlọ́run, nípa gbígba Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ. Kì í ṣe ohun tí ó le rárá, bóo ṣe rò, láti gbà á. Yàn, láti gbà á lónìí!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbési aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*